IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 562 MONDAY, MARCH 23, 1964 (2D)

## Ijọba Ibilẹ Eko Ti Gba Aṣẹ

EKO — Ni ojo Abameta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria fun Ijọba Ibilẹ Eko (L.C.C.) ni aṣẹ ati agbara lati ma gbe moto ti awọn onimọto ba gbe si oju titi kuro, ki nwọn si maa gbe awọn moto na lọ si Ile iṣẹ wọn.

Oniwe irohin wa Ejongboro ti o lọ si Ile Igbimọ Aṣofin na fi ye wa wipe Alhaji Musa Yar Adua, Minista Alamoju to Eto Igboro ilu Eko fun Apapọ Ijọba lo mu aba na wa wipe 'ki Ijọba ṣe ni ofin, ki awọn si fi aṣẹ si pe, ki awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko maa gbe mọto ti awọn onimọto ti nwọn ko bikita fun ẹmi ọmọ enia ba gbe si oju ọna kuro.

Ki Ijọba to gba ọrọ na, ki nwọn si to sọ di ofin Minista na ṣe alaye wipe ọpọlọpọ awọn onimọto ni nwọn ko bikita fun ẹmi ọmọ enia, ti nwọn ngbe mọto wọn si oju ọna, ti nwọn ngbe wọn si ọna, ti awọn onibasikulu ko si ni ri ọna gba ti mọto miran ba nbọ.

O tun ṣe alaye pe ọpọlọpọ ijamba ti o nṣẹlẹ nipa awọn ti o ngbe mọto wọn si oju ọna ni. Bi awọn onimọto ko ba maa gbe mọto si oju ọna mọ, ijamba yio dinku larin ilu Eko.

Nigbati o ṣe alaye rẹ tan ni Apapọ Ijọba wa fi aṣẹ si wipe, ẹnikẹni ko tun gbọdọ gbe mọto rẹ si oju ọna mọ larin igboro ilu Eko, ẹniti awọn ọlọpa aṣẹmọto ba si ri ti o gbe mọto rẹ si oju ọna, ki nwọn maa gbe mọto oluwarẹ lọ sinu ọgba ile iṣẹ Ijọba Ibilẹ Eko.

# AWỌN ẸGBẸ ODUDUWA FẸ ṢE AJỌ-NLA



ỌLỌLA OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ
AKỌWE AGBA ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA

EKO:- Irohin koto afojuba ni ipade gbogbog oo ti awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa ẹka ti Eko ṣe ninu Iga Olusi I Eko ni irọlẹ ọjọ Ẹti ti iṣe Ogunjọ oṣu yi, nitori pe, bi enia ju abẹrẹ silẹ kole de lẹ fun ọkẹ aimọye awọn ọmọ ẹgbẹ na to peju pesẹ sinu ipade na.

Ipade na bẹrẹ ni deede agogo mẹfa Irọle. Alufa Tesilimi Nasiru lofi adura kikon şi ıpade na labẹ Alaga Iya-afin Salamatu Fashina.

### AJỌYỌ PATAKI

Lẹhin adura Alhaji Yakubu dide, o ṣe alaye gẹgẹbi eto ti awọn ẹgbẹ na ti ṣe koja, ninu ipade gbogbogbo o ti ẹgbẹ na ṣe ni Muṣhin.

O si tun da ni imọran wipe, o tọ ki ẹgbẹ na ṣe ajọyọ pataki kan ni igboro Eko eyiti yio jẹ ti Ẹka Eko ati agbegbe re yio fi mọ wipe ẹgbẹ Oduduwa ko ku, o ṣẹṣẹ di araba ni.

Ki o to da imọran yi tan, ni tọmọde ati agba to nbẹ ninu ipade na sọ wipe awọn faramọ imọran na ati wipe awọn yio ṣe ariya na lẹkunrẹrẹ.

### IDANILOJU

Lẹhinna, ọgbẹni Fadipẹ ti iṣe akọwe agba na dide, ki o to ma sọrọ o koko dupẹ lọwọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ, o sọ fun wọn wipe on na faramọ imọran ti Alhaji Yakubu da ati pe, o jẹ ohun to dun mọ on ninu pupọ fun fifaramọ imọran na

Nitoripe, on mọ daju gbangba pe, gbogbo ohun to ba dara lati ilu Eko ni yio ti dide ati wipe, on ri daju wipe Eko lo mu ẹsẹ ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa duro.

Ọgbẹni Fadipẹ tun fi ibo ti Eko di fun awọn Igbimọ Ibilẹ ilu Eko wọle laipẹ yi kun ọrọ rẹ.

Lẹhin ọpọlọpọ alaye ati gẹgẹbi Eko ti duro gbọnin-gbọnin lẹhin Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, on na tun fi siwaju Ipade ọjọ na wipe o tọ ki ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa Ẹka Eko ni igbakeji Alaga.

Nibẹ ni Ọgbẹni Nasiru Adisa, ti dide, ti o sọ wipe, on da a ni imọran wipe, ki a fi Alhaji Yakubu ṣe igbakeji Alaga na, gbogbo ero ipade na si faramọ imọran rẹ.

Lẹhinna ni ọgbẹni Lawani Oluwo ọkan ninu ẹka ẹgbẹ Oduduwa lati Mushin dide o sọ wipe, inu on dun on jẹ ọkan ninu awọn ti o wa si ipade na ati wipe, o jẹ ohun to dun mọ on ninu ati ri wipe, nwọn fi Alhaji Yakubu ṣe igbakeji Alaga ẹka Eko.

### ẸGAN KOSI

Ori ti ko ba si ti ẹgan, Alhaji Yakubo to ẹniti a le fi ṣe Alaga na.

Lẹhin ọpọlọpọ alaye o pari ọrọ rẹ pẹlu adura, Lẹhin ti awọn enia jankan-jankan ti o wa sinu ipade na sọrọ tan nwọn pari ipade na pẹlu adura lati ọwọ Alhaji Amusa Adele.

Wo oju ewe Kẹfa

# Adura fun Awọn Imọle Oko-Ọdẹ To lọ Si Mẹkka Lọdun Yi

Lati ọwọ Akọwa Agba Ẹgbẹ

EKO:— Ẹgbẹ Nurudeen kesi gbogbo ọmọ Oko-Ọdẹ pe nwọn ku orire nipa awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn nlọ si ile Ọlọrun Mẹkka–Mẹdina, ki Oluwa na ṣe irin ajo na ni alalọbọ amin. Ẹku ipalẹmọ Ọlọrun yio sin nyin lọ yio tun sin nyin bọ. Bẹ ni Alhaji Saidu Nina lowo kesi gbogbo ọmọ Oko-ọdẹ paapa Ẹgbẹ Nurudeen Islamnejah pe ki wọn mo gbagbe awọn eto ti nwọn mọ se lọdọdun fun awọn ero Hadji to mọ nlọ.

Ki a mọ gbagbe awọn adura wa ni sisẹ nitoripe ko gbọdọ si erun loju ọmọ ẹgbẹ titi awọn tọ lọ si Haji yio fi de ki asi mọ gbagbe ipade ti aṣe ni ọjọ kẹdogun oṣu kẹta 15/3/64 ninu ọdun yi ni ibi ikomọjade Ọgbẹni Jimọh Alapoti Ipade na jẹ pataki fun awọn ọmọ ẹgbẹ wa A ṣe eto nla fun igbega ẹsin Anabiyi Muhammed (ikẹ ati ọla ko mọ bẹ fun) Ẹgbẹ Nurudeen Islamujah nṣe eto irẹpọ larin ilu, baba ẹgbẹ na Hadji Imam kesi gbogbo ọmọ ẹgbẹ pe ki nwọn mura lati ṣe eto pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ miran ti nwọn nlọ si Mekka-Mẹdina lọdun yi.

Hadji Saidu Ninalowo tun'ran awọn ẹgbẹ leti ipade ti ao ṣe fun alagba wa Hadji Bello ni Isalẹ Agbẹdẹ ni Eko ni ọjọ Isinmi ti nbọ yi ti ṣe ọjọ kejilelogun oṣu kẹta ọdun yi (22/3/64) A nfẹ ki ẹse awọn ọmọ Oko Ọdẹ pe sibi ipade na Adura na yio bẹrẹ ni agogo mẹjọ alẹ (8 p.m)

Awọn Alufa ọjọ na ni Hadija Iman Aliyu ati Hadji Kuranga, bakanna ni a tun nran awọn ọmọ ẹgbẹ na leti pe, ki ẹ mọ ṣe alaiwa sibi adura Aileru Owoyale ti ao tun ṣe ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹta (24/3/64) ninu ọdun yi ni Shomolu; a o tun ṣe adura ti Hadji Yusufu Kekere ni ọjọ Jimọh ti ṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn osu kẹta (27/3/64) ọdun yi ni dede agogo mẹjọ (8p.m.) alẹ

Ẹ ma tun gbagbe adura ti Kuranga Alupako ti ao tun ṣe ni ọjọ Aba-Mẹta ti ṣe ọjọ kejidinlọgbọn (28.3 64) oṣu kẹta ọdun yi ao ṣe ni Nọmba 102, Ọdunfa Street, Eko

Bakanna ni a o tun nfẹ ki ẹse gbogbo wa pe ni ọjọ Isinmi ti ṣe ọjọ kọkandinlogbọn osu kẹta (29.3 64) ọdun yi Ki gbogbo wa pe sibẹ pẹlu owo wa Ọlọrun yio ran wa lọwọ amin

Mo fi Ọlọrun bẹ gbogbo ẹnyin ọmọ Ibilẹ Oko-Ọdẹ pe, ki wọn pese sibi gbogbo awọn adura na, Oluwa yio fi ire kari gbogbo wa o amin.


## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Ẹgbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Ẹgbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ agbẹdu, ikọ–ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati loru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ola Ita Faji)


# Ẹniti O Ba Ni Ẹti Ki O Gbọ

Lati ọwọ HADJI Y. A. DISU

Olotu, mo ṣe akiyesi pe, o nsa gbogbo ọpọlọ ati gbogbo agbara rẹ lati maa wa oriṣiriṣi irohin aladun ati awọn irohin akakọgbọn sinu iwe rẹ, Irohin Imọlẹ, nigbagbogbo Nitorina ni ọkẹaimọye enia ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Ipinle Ila Orun, Ipinlẹ Iha Gusu paapa L'Eko maa ṣe nka a lojoju mọ lakaye ati laka tun ka.

Lati ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ti mo ti kọ iwe "Ẹ ku ipọmọ" sinu iwe Irohin Imọlẹ ni ọpọlọpọ enia l ọkunrin ati l obinrin ti nbi mi pe, e tiṣe ti alapakan enia tabi ọmọ ẹru ẹru fẹran lati maa huwa ijamba ọlọṣa ti o nko aṣọ alaṣọ ti nwọn se "rigimọ' ti nwọn nṣe abosi, ti nwọn maa fi nṣe ẹrẹkẹ ebu, ti nwọn si maa fi nfọnu ?



Alhaji Y. A. Disu

Mo ri pe, nko ri aye to lati maa ṣe alaye na fun awọn onibere na lọkankan. Mo bẹ nyin olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe nyin lati fesi na fun wọn, inu mi yio si dun pupo bi ẹ ba gba mi ni aye na, a dupẹ o.

Alapakan tabi ọmọ ẹrukẹru dabi ọmọ enia ti o burẹwa. Ọmọ enia ti o ba si burẹwa fẹran lati maa fọnnu gba ara rẹ silẹ.

Ẹlẹrẹkẹ ebu ni wọn, wọn rii pe, awọn ko nyayi, a ni, nwọn rii pe, awọn ko pe ki awọn onija wọn to fi abuku kan wọn, nwọn yio tete gba waju gbẹhin lati ra ebu fun wọn. Ẹnu wọn maa ndun pupọ, ka fọnru si ni wọn nwọn a si ma bu ramuramu bi kiniun lori ofo.

Ọkan ninu awọn idi pataki na niyi o ti nwọn ki saba fi irufẹ alapakan bẹ ẹ jẹ oye aṣiwaju esin ni Mẹkka, Mẹdina ati Jerusalẹm.

Ni ilu miran ti ẹsin Islam ranlẹ nibẹ, ni Naijiria, gẹgẹ bi Ilọrin Isẹyin ati Eko, nwọn ki i fẹ lati fi alapakan jẹ oye na. Ẹni ti nwọn bire ni idi iya ati ni idi baba ti o si ni imọ ati iwa ọmọluwabi ti ki ṣe kẹnimani kẹnimani ti ko si lọ ko aṣọ alaṣọ tabi ẹnikeji ta ni nwọn ma fi ẹni bẹ jẹ oye Lemọmu tabi oye, alufa Ṣọọsi.

Ẹni ti o ba si nfẹ ki nwọn fi on jẹ ẹ, ti nwọn ko ba fi jẹ, ko gbọdọ binu sodi de aye ti yio ma a fi sa fun maṣalasi tabi ṣọọsi. De aye ti yio ma a fi da irun ki ninu ile rẹ

O lodi si ẹsin Islam lati ma a ba mọṣalasi yan odi, O di ko dara. Ẹ ronu piwada. Ki Ọlọrun si tọ gbogbo wa sọna o

Mo tẹnumọ ọ fun nyin, mo si fẹ ki ẹ mọ dada pe gbogbo iwa abeṣe ti o wa lara awọn abilẹjẹ alapakan ni nwọn ma a ntete fi nbu ẹni ti o ba ti san ju wọn lọ Eebu ni nwọn ma a nṣe Nwọn yio si ko awọn ẹni "Ikọkukọ" buburu, a ni awọn ẹni esi bi ti wọn mọra Nwọn yio ma a kọ wọn ni ikọkukọ si ni ti o ba san ju wọn lọ, ti o si mọ wọn daada ti ko ti gba gbẹrẹ fun wọn Oru ijamba ni wọn. Eleṣu ni wọn Opurọ ni wọn, E lọ sọ ara nyin pupọ lọdọ wọn. Ẹniti o ba ni eti lati fi gbọki o gbọ.

## Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# A.B.D. Olowe

LATI OWO:— SURAKATU BADEKALẸ

A. Agbọn ta baba ni agbọn, o binu ju agbọn silẹ.
B. Baba njona ẹ mbere Irughọn
D. Dada ko 'e ja ṣugbọn o ni aburo to gboju.

E. Elegede so loko asonpa nbinu
Ẹ. Ẹnito gbe oku Aparo gbe apọn
F. Fija rẹ fun Ọlọrun ja fọwọ lẹran.

G. Gele o dun bi ka mọwe, ka mọ we o dun bi ko yẹ ni.
GB. Gbangba d'ekun kedere bẹ wo.
I. Itakun to ni ki Erin ma gun Oke odo, on ati Erin lo nlọ.

H. Haramu ni Ole jija, ẹ maṣe jale mo.
J. Janduku ọmọ ajitafa, ọjọ ti o tutu ba mu gbogbo enia ni Oru ma nmuu'
K. Kawa ẹnito lehin ka f'ọmọ fun Abuke lọ gbẹhin silẹ.
L. Labalaba to ba digbolẹgun aṣọ rẹ a faya.
M. Malu ti ko ni iru Oluwa Oba ni nle eṣinṣin fun un.
N. Nangudu ku tan ko ri eni jẹ on ṣugbọn Erin ku Nangudu fi jẹ, Ẹfọn ku loko Nangudu kan na fi jẹ pẹlu.

O. Oiuba irẹ ko denu aṣẹhin deni ko wọpọ.
Ọ. Ọpọlọpọ enia ni ko mọ pe ọpọlọ ni ọpọlọ lori.
P. Purọ nniyi ẹtẹ la omu wa

R. Riro ni ti enia ṣiṣe ni t'Ọlọrun.
Ṣ. Ṣiṣe ṣiṣe ni ọmọde ulu ilu Epo.

T. Tanimọwo afi Oluwa
U. Ukuuku de Gambari de awo ri awo

W. Were dun wo l'ọja Asin win ṣe mu ṣe ẹrin rin tani jẹ bi iru wọn lọmọ.
Y. Yọkọlu, yokọlu ko wa tan bi Iyawo gbọkọ sanle ọkọ y ke

## * YẸ IRAWỌ RẸ WO *

AQUARIUS (Jan. 20 - Feb. 18) Iwọ yio je igbadun ara rẹ ni ọse yi, awọn ọrẹ yio se iranlọwọ pupọ fun ọ.

PISCES (Feb. 19 March 20) Nipa iranlọwọ ọrẹ ni iwọ yio se gbe ẹru rẹ dori. Maṣe bẹru, iwọ yio bori.

ARIES (Mar. 21 - April 19) Bi o tilẹ jẹ pe ọsẹ yi yio le fun ọ, ko ko ko, awọn ẹgbẹ ni yio gbe ọ bori iṣoro gbogbo. Maṣe jina si awọn ọrẹ rẹ ninu ọsẹ yi.

TAURUS (April 20 - May 20) Orire yio jẹ tirẹ lọse yi, itẹlọrun yio si wa fun ọ, epọ ninu awọn iia iwọ pẹlu ọrẹ yio pari si rere.

GEMINI (May 21 - June 21) Iwọ yio ṣe orire larin ọsẹ yi, irinajo si mbẹ lẹse rẹ. iwọ yio ni ọrẹ titun kan ti yio ṣe ọ ni anfani, o le ṣe ọkunrin tabi obinrin.

CANCER (June 22-July 22) Ọrọ kan yio ru ọ loju lọsẹ yi, sugbọn awọn ọrẹ yio yọ ọ ninu ijangbọn na. Iṣẹ rẹ yio dara pelu, iwọ sa te siwaju, ki o si gbiyanju.

LEO (July 23-Aug 22) Ọsẹ yi yio dara fun ọ, iwọ o si ri iṣẹ pupọ ṣe, Iwọ o si gbalejo pupọ

VIRGO (Aug 23-Sept 22) Irewesi ọkan yio wa fun ọ ọse yi gbogbo nkan ti o nlepa ko ni ṣe deede, suru li ẹbọ

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Ojọ oni dara pupọ fun o, bi o ti lẹjẹ pe iwọ ko le ṣe ki o maṣe ri idaduro diẹ sa fi ori tii

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ọse yi dara fun ọ, iwọ o si jẹ, gbadura ara rẹ, iwọ o si gba lejo ti yio dun mọ ọ ninu

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ko ni si idamu tabi wahala fun ọ lọsẹ yi Ọrọ rẹ kan yio gba o ni imọran, ki o gba a fi ṣe Ogbọn nitori imọran na dara pupọ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Arẹ ọkan yio ba ọ ja ọsẹ yi Ṣugbọn arẹ na ko ni pẹ kuro. Nipa suru ati fọkan bale ni iwọ yio fi bori iṣoro gbogbo.

# AKARA TU 'SEPO!

## Iwe Itumọ Ala na ti de !!



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ re Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan

# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI



## "CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wà lara rẹ o si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe se igbọnse. Arun Jẹdijẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkuarin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan re patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti won a ma polowo won fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mewa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lowọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ ivọnu rẹ yio si tun berẹ bakana. Orişiriṣi Jedijedi ni o wa eleni ti o berẹ nipa aiko ma se igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ewẹ nipa jije Suga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jedijedi orişiriṣi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lehin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹẹ wa idi rẹ ra ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lowọ Jẹdi patapata alafia yio de si ẹkeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi to wa ni igboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IWE SI OLOTU

## Ẹ tu Ile Igbimọ Iwọ-Orun ka

Olotu, Gba mi laye lati kesi Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, Oloye S.L. Akintọla wipe ki o tete tu ile Igbimọ aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun ka, ki a le tete dibo kia ki a fi le mọ ipo ti awọn ẹgbẹ oṣelu kọọkan wa ni Ipinlẹ yi.

Nitoripe, ọrọ o ni ẹgbẹ tuntun Ọla ẹgbẹ miran ko jẹ ki ale mọ ipo ti awọn ẹgbẹ na wa ninu Ile Igbimọ Aṣofin.

Yio si dara pupọ ti a ba tete dibo laipẹ yi, ki a le fi mọ daju-daju ẹgbẹ ti awọn enia nfe ki o ma a ṣe Alakoso Ijọba Ipinle na lai si isiyemeji rara.

Mo dupẹ lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
I. A. OKUNLỌLA
Ikirun.

## Ẹ Din Owo Bode Aṣọ Ku

Olotu, Ayọ nla ni yio jẹ fun mi ti Olotu ba le gba mi laye lati fi Iwe mi yi bẹbẹ si Minista Alamojuto eto owo fun Apapọ Ijọba N a i j i r i a, Oloye Festus Okotie Eboh, wipe ki o ṣe iranlọwọ lati le ripe owo bode lori ọja bi aṣọ din owo ku ki awọn mẹkunnu o le ma a ri aṣọ wọ ni arin ilu.

Nitori pe lai pẹ yi ni a gbọ wipe Ijọba tun fi owo kun awọn ọja kan.

Iru alekun owo bode yi ko le ṣe anfani fun awọn oniṣowo rara.

Bẹni ko tun jẹ irọrun fun awọn mẹkunnu gbogbo ti ko ni agbara lati ra awọn ọja ti owo rẹ ba ga.

Ọrọ yi di ọwọ nyin, mo fẹ ki ẹ fi ọrọ na si eto.

Mo dupẹ pupọ lọw nyin Olotu, ọwọ nyin yio ma roke.

Emi ni,
J. A. ADESHILE
Awẹ.

## Ẹ Fi Iwe Ijala Na Ranṣẹ Si wa

Olotu, inu mi yio dun ti ẹ ba le tẹ iwe mi yi jade ninu Iwe Irohin nyin aladun yi.

Mo fẹ dupe pupọ lọwọ Ọgbẹni wa Ọladipọ Yemitan fun akitiyan rẹ lori bi o ṣe ko ọrọ ijala rẹ jọ ni ede-Yoruba.

Mo fẹ ki Olotu ṣe agbara ki awa ti a wa ni ilẹ Dahomi le ra ninu Iwe Ijala Are Ọdẹ na ki anfani na le kan wa.

Mo dupẹ pupọ lọwọ ayin Olotu.

Emi ni,
BUSARI AJADE.
Pram-Dahomey.

## E la Ẹyi Ye Mi

Olotu, jọwọ inu mi yio dun gidigdi bi ọ ba le ṣe alaiye owe ti nwọn npa bayi fun mi wipe "Amunibuni ẹran Ibiyẹ, ọrọ ati idi owe na ko ye mi rara, ẹ ladi rẹ yo mi.

IDAHUN

Owe ni ẹṣin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu owe ni a fi nwa Nitorọ ni awọn baba wa npa owe wipe Amuni buni li ẹran Ibiyẹ. Ibiyẹ foju, ẹran rẹ na si fọju. Bi ọrọ owe na ti lọ n yi:-

Obinrin gbajumọ kan wa ni Isalẹ-Eko, ti nwọn npe ni Ibiyẹ. on si ni onse Eko nigbani. Ojẹ ẹnji o lọla, ti o si niyi larin ilu Eko,, gbogbo ẹgbẹ ati Ọgba lo mbọwọ fun un nigbana.

Ibiye ni Ewurẹ kan ti o fọ oju kan lẹhin na ni Ibiyẹ fun ra rẹ se aisan, osi fọ oju mejẹji Ni ẹhin kule ibiti Ibiyẹ ngbe, ni nwọn ti nna ọja kan, gbogbo ọrọ ti nwọn ba nsọ ni ọja yi ni Ibiyẹ ma ngbọ ninu ile rẹ,

Nigbati ẹran-yọ Ibiba tẹnu bọ Gari, tabi Ẹwa wọn, nṣe ni awọn olu ni kumọ, Bi oba tun ṣe diẹ, ẹran na yo tun pada wa tẹnu bọ ọja wọn Nigbati nwọn ba lu ẹran na ti oba su wọn ni nwọn o wipe kini tilẹ ṣe ẹran afọju yi.

Were ni ẹniti o ọrọ yio fi ọwọ bo ẹnu yio wipe on sọrọ si agbọn Ibiyẹ vio rope oju on ti ọfọ ni nwọn nfi on se yẹyẹ ni ọja, Ṣugbọn awọn to sọrọ ko lero bẹ, ẹran Ibiyẹ ni nwọn nbu.

Eyi lo mu wọn lati ma powe wipe Amunibuni ẹran Ibiyẹ, tabi ẹran eni lo ngmu ni jẹ ẹgbin.

Ẹku iṣe o, ajinde ara yio ma a je o.

Emi ni
ẸSHỌ
Eko

## Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU

AH! REMEMBER THAT

# The Social Dandies

*PRESENTS*

## An Eid–Ul–Kabir Dance

AT

FORESTER CENTENARY HALL

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/– Flat**

Tikets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, I r o h i n Imọlẹ Offices. Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta,

BERE OJU OWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yato patapata si awọn

**RICHALET** Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyen ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹṣẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Bere egbogi ajebina Payal y ni ṣọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street Yaba

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE MARCH 23 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABEOKUTA — — — — | Atan, Agbado. Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN — — — — — | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba okuta' Ijaiye-Orile |
| IJEBU — — — — — | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpẹ ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJESHA — — — — — — | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| EGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ IṢẸGUN MARCH 24 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Ilawọ |
| IBADAN — — — — — | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — — | Ikẹnẹ, Ọkun-Ọwa Erowọ Omu Mamu |
| JẸSHA — — — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo Idoko Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | gbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI — — — — — — | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ'RU MARCH 25 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute- Ero Ọjọ Ajid |
| ABẸOKUTA — — — — | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọl Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN — — — — — | Lalnpọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU — — — — — — | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA — — — — — | Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO — — — — — | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ MARCH 25 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN — — — — — | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU — — — — — — | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| JẸSHA — — — — — — | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO — — — — — | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI — — — — — — | Ilogbo, Ishan. |

## ỌJỌ ẸTI MARCH 27 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA — — — — | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Fabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN — — — — — | ẹdẹgbọ, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda, Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU — — — — — | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA — — — — — — | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO — — — — — | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI — — — — — — | Egosi, Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ ABAMẸTA MARCH 28 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagary |
| ABẸOKUTA — — — — — | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN — — — ... — | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU — — — — — — | Ikẹonẹ, Ọkun—Owa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA — — — — — — | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO — — — — — | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI — — — — — — | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU MARCH 29 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | keja, Agege |
| ABẸOKUTA — — — — — | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo. |
| IBADAN — — — — — — | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU — — — — — — — | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope |
| IJẸSHA — — — — — — — | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun |
| ẸGBADO — — — — — — | Ijẹbu-Ijẹsha Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI — — — — — — — | Okemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ AJE MARCH 30 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA — — — — | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasinm Owode |
| IBADAN — — — — | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU — — — — .. | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itelo, Ode-Rẹmọ |
| IJẸSHA — — — — — | Ibodi, Ibode Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO — — — — | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, ṣunwa, Iboro |
| EKITI — — — — — | Ilogbo, Ishan |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJON'GBORO

### IKẸJA

Apapọ Ijọba Naijiria ti ṣi Ile ifiweranṣẹ kan si Ikẹja ninu ọsẹ ti o koja yi.

### BỌMBAY

Ọkunrin kan ti o pa ọkọlokoji rẹ nitoripe o ba nibiti o gbe mba iyawo rẹ lopọ ti nwọn ṣe idajọ ẹwọn ọjọ kan fun ninu odun 1959 ni Ijọba da silẹ ninu ọsẹ ti o kọja yi.

### JOHANNESBURG

Gbogbo awọn ara ilu bẹrẹsi sare lọ wo ọmọbinrin kan ti o nlọ si ile iwe ni gbati o bimọ kan. Ọmọ ọdọn mọkanla ni ọmọbinrin ti o fi bimọ.

### ABẸOKUTA

Adajọ Ile ẹjo giga ti ṣe idajọ pe, ki ọdaran kan, Karimu Akanji ti o nwa mọto takisi o lọ si ẹwọn ọdun meji nitoipe o wa mọto ni iwakuwa, o si pa obinrin.

### MUSHIN

Ọrọ di pẹẹntuka nigbati awọn ọlọpa wọle ti nwọn si ragaba ọdaran kan, Ramọnu Aminu, nitoripe nwọn ni o jẹ ọkan ninu awọn ọlọpa ti nwọn lọ fi mọto ko aguntan niadugbo Ọlorunsogo.

### EKO

Ijọba Ibilẹ Eko se ikede ninu ọsẹ ti o kọja wipe, ẹgbaa mẹiọ (18,000) awọn ọmọde ni nwọn bẹrẹ Ile-iwe ni Eko ninu ọdun yi

### APAPA

Awọn ọlọpa ti bẹrẹsi wa awọn obi ọmọkunrin kan, ẹni ọdun meji ti nwọn ri oku rẹ ninu odo ọsa

### ASABA

Awọn ọlọpa ti mu awọn ọkunrin mẹta kan nitoripe nwọn ji awọn ọmọ Ile Iwe mẹrinla gbe a si lero pe awọn ọdaran na yio fara han niwaju Adajọ loni.

### KAFANCHAN

Ọrọ di bi o lọ ki o ya fun mi nigbati adajọ kotu se dajọ pe ki ọdaran kan lọ si ẹwọn odun mẹrin nitoripe, o ji pọnun merin gbe bi ọkunrin na ti sare si adajọ lori aga ni adajọ ba sa jade

### EKO

Oloye Fred Anyiam akọwe ẹgbẹ Alakukọ ti kesi gbogbo awọn oniwe irohin wipe ki o dakẹ ki nwọn o maṣe maa dakun ọrọ awọn ẹgbẹ oṣelu ti o dẹlẹ yi.

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 562 MONDAY MARCH 23, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lehinti mo ti se abewo kakiri Ile Naijiria ati Ghana, o dabi enipe opolopo enia ni nwon nro wipe Iwe Irohin Imole ati Iwe Irohin Akintola ti awon npe ni Imole Owuro okan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki ise be rara asi fe fi ye gbogbo enia ki o ye won wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imole daduro ko faramo egbe oselu kankan ko si ni ohunkohun se pelu Imole Owuro.

Iwe Irohin Akintola ti nwon nte ni Ibadan ni ongbenuse fun egbe Akintola Ibadan ni nwon gbe nte Imole Owuro, Eko ni a gbe nte Iwe Irohin Imole lati odun meje (1957) sehin.

Ao se ifilo yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbo, sugbon eniti o ba tun fe alaye lori oro yi le kowe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Ise Irohin Imole ni nomba

16, BAMGBOSE STREET,
PHONE 985, LAGOS

# OLOYE OSADEBAY SO PE KI A MA GBADURA

IBINNI:– Olotu Ijoba Ipinle Agbedemeji Iwo Orun Naijiria Oloye Dennis Osadebay ti kesi gbogbo awon onigbagbo ile Isin ti owa ni gbogbo ile Naijiria wipe ki nwon ya ojo kan soto lati le fi gbadura si Olorun ki oro eto ikania ma ba le da rudurudu sile nile wa larin awon Asiwaju egbe Oselu.

Oloye Osadebay ti kesi Olola Abubakar tise Alakoso Apapo Ijoba ile Naijiria larin ose ti okoja ti o si ti roo lati petu si rogbodiyan ti ole sele tori abayori eto ikania na.

Irohin fi ye wa wipe larin ose ti o koja yi ni Olola Abubakar fesi si iwe kan ti Oloye Osadebay ko si, o si dupe pupo lowo re fun gbo gbo imoran ti Oloye Osadebay da fun un bi yio se pe ipade awon alakoso Ijoba ile Naijiria.

Oro ti Oloye Osadebay kesi awon ile isin Olorun pe ki nwon gbadura, jade nibi ase apeje kan ti nwon se fun un ni ile isin awon Aguda ti ilu Ibinni nipari ose ti o koja yi

Oloye Osadebay fihan gbogbo enia wipe, ohun bu buru ni fun awon ti o fi oro eto ikania yi se oro iselu.

O ni ohun ti o ye ni pe ki gbogbo Ipinle kokan ti o wa ni ile Naijiria ni iye asoju kanna ninu ile Igbimo Asofin ti Apapo ile Naijiria.

O kilo fun gbogbo awon enia wipe ki nwon jawo kuro ninu madaru oro abayori eto ikania ti o wa nile yi, ki nwon o si dojuko awon ise pataki miran ti o le mu orile ede wa Naijiria laye pataki ti awon enia aiye yio fi mo wipe, a kosi ominira wa lo.


make it a successful SEASON with MERCEDES-BENZ TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


## Awon Egbe Oduduwa Fe Se Ajo–Nla

Lati oju ewe Kini

Die ninu awon enia pataki ti a le daruko ninu ipade ojo na ni awon bi-

Omo Oba L. A. Ojora, Alhaj A. K. Bello Omo Oba Ade. Adefarakan, S. A. Oshodi, Adeyemi Fadipe, G. B. A. Akinyede (Amofin) Alhaji Yakubu, Lawani Oluwo, ati awon Iya egbe oja bi-:

Iya-egbe Grace Odeku lati oja Owode, Iya-egbe Abibatu Folaji, lati Ebute Elefun, Iya-egbe Salamotu Fashina lati oja Ajelogo, ati Iya-egbe Safuratu Adejoke lati oja Itafaji ati opolopo awon Omo egbe won ti aye ko gba lati daruko won sihin.

Ki awon omo egbe na to tuka ni ojo na, gbogbo won lo gba wipe awon yio ma a mura sile fun Ajo-nla ti awon omo egbe na fe se laipe.


Pinted and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yaba Lagos (23/3/64)